# ỌDUN JUBELI

## Lefitiku 25:1-46

## ẸKỌ 89 – FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ẹmi OLUWA Jehofah mbẹ lara mi: nitori o ti fi ami ororo yàn mi lati wãsu ihin-rere fun awọn òtoṣi; o ti rán mi lati ṣe awotán awọn onirobinujẹ ọkàn, lati kede idasilẹ fun awọn igbekùn, ati iṣisilẹ tubu fun awọn ondè" (Isaiah 61:1).**

**I Aṣẹ lati Oke Sinai**

1. Oluwa sọ fun Mose lati ori Oke Sinai pe ki wọn pa ọdun Isinmi kan mọ́ nigba ti wọn ba de ilẹ naa ti Oun yoo fun wọn, Lefitiku 25:1, 2
2. Ọdun mẹfa ni wọn o fi gbin irugbin ti wọn o si maa kore, Lefitiku 25:3; Ẹksodu 23:10
3. Ọdun keje yoo jẹ́ ọdun isinmi, Isinmi kan fun Oluwa, Lefitiku 25:4; Heberu 4:9
4. Awọn ati awọn ti i ṣe alejo laaarin wọn yoo jẹ irugbin ti o ba la ilẹ hù, Lefitiku 25:5-7; 2 Awọn Ọba 19:29

**II Ni Aadọta Ọdun**

5. Wọn yoo ka ọdun Isinmi meje, tabi ọdun mọkan-din-laadọta, Lefitiku 25:8
6. Ipè Jubeli ni lati dún ni Ọjọ Etutu jakejado gbogbo ilẹ naa, Lefitiku 25:9
7. Nigba ti o ba di aadọta ọdun geere ni yoo jẹ́ ọdun Jubeli tabi ọdun idasilẹ. Olukuluku ẹni ti a ti ta ohun ini rẹ̀ ni a gbọdọ dá ohun naa pada fún, Lefitiku 25:10-13; Isaiah 61:1, 2; 63:4; Luku 4:19
8. Bi wọn ba ti tà tabi rà ini wọn, ki wọn ki o bu owó rẹ̀ gẹgẹ bi iye ọdun, tabi ki wọn ṣiro lati ọdun Jubeli ti o ti kọja, ki wọn si bu owó rẹ̀ bẹẹ gẹgẹ, Lefitiku 25:14-16; 27:17-25
9. Wọn kò gbọdọ ni ọmọnikeji wọn lara, bikoṣe ki wọn bẹru Ọlọrun, Lefitiku 25:17-19

**III Ọpọlọpọ Eso**

10. Bi wọn ba si wi pe ki ni awọn o ha maa jẹ ni ọdun keje, Oluwa sọ fun wọn pe Oun yoo bù si eso wọn ni ọdun kẹfa, eso oko wọn yoo tó fun ọdun mẹta, Lefitiku 25:20, 21
11. Wọn yoo gbin irugbin ni ọdun kẹjọ, sibẹ ninu eso ti ọdun iṣaaju ni wọn o maa jẹ titi di ọdun kẹsan-an, Lefitiku 25:22; Jọṣua 5:11, 12

**I Irapada Ilẹ Naa**

12. Wọn kò gbọdọ ta ilẹ naa laelae niwọn bi o ti jẹ ti Ọlọrun, Lefitiku 25:23, 24
13. Bi ipọnju ba mu ki a ta a, ibatan onilẹ naa le ra a pada ṣiwaju ọdun Jubeli; ṣugbọn bi ko ba le ra a pada, a o da a pada si ọwọ ẹni ti o ni in ni ọdun Jubeli, Lefitiku 25:25-28
14. A fun wọn ni ofin nipa tita ilẹ ti o wà ni ilu olodi ati eyi ti kò si ni ilu olodi, ati eyi ti o jẹ́ ti awọn ọmọ Lefi, Lefitiku 25:29-34
15. Ki wọn ki o ma ṣe gba owo èlé lọwọ arakunrin kan tabi ki wọn fi ṣe ẹrú, Lefitiku 25:35-42; 1 Kọrinti 7:23
16. Wọn kò gbọdọ mu ipọnju tabi inira bá arakunrin ti o wà labẹ akoso wọn, Lefitiku 25:43-46; Efesu 6:9; Kolosse 4:1

## ALAYE

**Ọdun Jubeli -- Apẹẹrẹ**

Ọdun Jubeli dabi ẹni pe o jẹ́ apẹẹrẹ igba ayé Ihinrere yii, ti Ọlọrun n gba gbogbo awọn ti o gba Kristi gbọ́ là kuro ni oko-ẹrú ẹ̀ṣẹ ti a si n fun wọn ni ẹtọ si ogún kan laaarin awọn ti a sọdimimọ́ ninu Kristi Jesu. Ọdun idasilẹ patapata ni i ṣe, idasilẹ ti igbese, ti iṣẹ́, ti ẹrukunrin ati ẹrubinrin, ti ilẹ ati ohun ini ti a tà lati inu idile tabi ẹya ti wọn ti wá.

Wọn ni lati gbìn ki wọn si ká eso oko wọn fun ọdun mẹfa, ṣugbọn ni ọdun keje wọn kò gbọdọ gbìn bẹẹ ni wọn kò gbọdọ kore. Oluwa yoo rán ibukun Rẹ̀ sori eso wọn ni ọdun kẹfa, oko wọn yoo si mu ọpọlọpọ eso jade tó iwọn ti ọdun mẹta papọ̀. Eyi jẹ́ iṣẹ́ iyanu nla, Ọlọrun nikan ṣoṣo ni o si le ṣe ileri iru ohun nla bẹẹ.

Ọdun keje yoo jẹ́ ọdun isinmi, Isinmi fun Oluwa. Awọn ati ilẹ wọn, ati ẹran ọsin wọn ni yoo ni isinmi ọdun kan jálẹ̀. Nigba ti wọn ba ti ṣe ọdun Isinmi yii lẹẹmeje, ti àròpọ̀ iye ọdun wọnni jẹ́ mọkan-din-laadọta, wọn o tun ni Isinmi kan. Ọdun kan ti o tẹle aropọ ọdun mọkan-din-laadọta (ọdun meje lọna meje) yii, yoo jẹ Ọdun Jubeli, ajigbese ki yoo tun san gbese ti o jẹ mọ́, a si gbọdọ dá ohun ini pada fun ẹni ti o ni in.

**Ofin ti o mú Eniyan Gbogbo Dọgba**

Iwọnyi ni akojọ awọn ofin ti o dara ju lọ ti a ti i fi fun eniyan rí lati fi nnkan si eto laaarin oniṣẹ ati alagbaṣe. Ayè ko si fun olowo lati fi iya jẹ talaka, bakan naa ni kò si aye fun talaka lati ṣe ọ̀lẹ. Wọn ni lati ka ara wọn si ọgbọọgba gẹgẹ bi arakunrin si arakunrin. Bi wọn ba pa ofin wọnyii mọ́ daradara, ohun gbogbo ni yoo wà ni idọ́gba laaarin awọn eniyan.

Dajudaju ohun ti o pilẹ awọn ofin wọnyii ni lati ṣe idena fun awọn olowo ki wọn ma ba sọ awọn talaka di ẹrú, ati pe ki gbogbo ilẹ má ba jẹ ini iwọnba eniyan diẹ.

**Sedekiah**

Ni akoko Jeremiah nigba ti ọba Babiloni n bá Sedekiah ọba Juda jà, Sedekiah ba gbogbo eniyan Jerusalẹmu dá majẹmu kan pe oun o fi ominira fun gbogbo wọn; olukuluku wọn si gbọdọ jẹ ki awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀ lọ lọfẹẹ (Jeremiah

34:8, 9). Awọn eniyan gba bẹẹ wọn si dá awọn eniyan wọn silẹ ki wọn lọ. Ṣugbọn lẹyin naa, wọn yí pada wọn si tun lọ mu awọn iranṣẹ wọnni pada sinu isinru. Inu Oluwa kò dun si majẹmu ti wọn bajẹ yii; Oluwa rán Jeremiah si wọn pe, “Wò o, emi o kede omnira fun nyin, li OLUWA wi, si idà, si ajakalẹ-àrun ati si ìyan, emi o si fi nyin fun iwọsi ni gbogbo ijọba ilẹ aiye” (Jeremiah 34:17).

Oluwa ti sọ fun wọn ni ibẹrẹ pe bi wọn kò ba gbọran si ilana Oun, Oun yoo tú wọn ká si aarin awọn Keferi, Oun yoo si sọ ilẹ wọn di ahoro. “Nigbana ni ilẹ na yoo ní isimi rẹ, ni gbogbo ọjọ́ idahoro rẹ̀, ẹnyin o si wà ni ilẹ awọn ọtá nyin; nigbana ni ilẹ yio simi, ti yio si ní isimi rẹ. Ni gbogbo ọjọ́ idahoro rẹ̀ ni yio ma simi; nitoripe on kò simi li ọjọ́-isimi nyin, nigbati ẹnyin ngbé inu rẹ̀” (Lefitiku 26:34, 35).

Oluwa fi àyè silẹ ki ọta kó awọn Ọmọ Israẹli lọ si oko-ẹrú ni ilẹ Babiloni, wọn si wà nibẹ fun aadọrin ọdun titi ilẹ naa fi san ọdun Isinmi rẹ̀ (2 Kronika 36:21).

**Irapada Nipasẹ Kristi**

Awa ti jẹ́ ẹrú eṣu rí; a ti ta ara wa fun asán; a ko si ni ẹ̀tọ́ si Ọrun ati awọn ogo rẹ̀ ayeraye. Ṣugbọn “igbati awa jẹ alailera, li akokò ti o yẹ, Kristi kú” fun wa – awa alaiwa-bi-Ọlọrun – Oun rà wá pada nipa Ẹjẹ Rẹ̀ iyebiye, O si ti fun wa ni ogún kan ti ki i dibajẹ, ti ko labawọn, ti ki si i ṣá.

Luku kọ akọsilẹ ọ̀kan ninu awọn iwaasu Kristi ni ibẹrẹ iṣẹ iranṣẹ Rẹ̀ pe, “Nigbati o si ṣí iwe na, o ri ibiti a gbé kọ ọ pe, Ẹmi Oluwa mbẹ lara mi, nitoriti o ti fi àmi oróro yàn mi lati wasu ihinrere fun awọn òtoṣi; o ti rán mi wá lati ṣe iwosan awọn ọkàn onirobinujẹ, lati wasu idasilẹ fun awọn igbekun, itunriran fun awọn afọju, ati lati jọwọ awọn ti a pa lara lọwọ, lati kede ọdún itẹwọgba Oluwa. O si pa iwe na de, o tun fi i fun iranṣẹ, o si joko. Gbogbo awọn ti o mbẹ ninu sinagogu si tẹjumọ ọ. O si bẹ̀rẹ si iwi fun wọn pe, Loni ni Iwe-mimọ́ yi ṣẹ li etí nyin” (Luku 4:17-21). Ọdún Jubeli tootọ ti dé. Olukuluku ẹlẹṣẹ ti a ti kó lẹru le lọ lọfẹẹ nisisiyii. Ogún ti a ti sọnu nipasẹ Adamu ni a le dá pada nipasẹ Jesu Kristi. Dajudaju ọdún itẹwọgba Oluwa ti dé.

**Ọjọ Etutu**

Jesu kò le ṣai kú fun ẹ̀ṣẹ awọn eniyan ki wọn le lọ lọfẹẹ. Ominira tabi irapada kuro ninu isinru ẹ̀ṣẹ ti a kede rẹ̀ nipasẹ Ihinrere ni a mu ki o dá ni loju ni igba Etutu nla nì ninu eyi ti a fi Jesu Oluwa rubọ.

A maa n kede Ọdun Jubeli nipa fifun ipè. Ni opin ohun gbogbo Jesu sọ nipa ara Rẹ̀ pe, “Yio si rán awọn angẹli rẹ̀ ti awọn ti ohùn ipè nla, nwọn o si kó gbogbo awọn ayanfẹ rẹ̀ lati ori igun mẹrẹrin aiye jọ, lati ikangun ọrun kan lọ de ikangun keji” (Matteu 24:31).

Lẹyin naa ni Isinmi nla ti Ọlọrun ṣeto rẹ̀ yoo dé, Jubeli ologo fun ẹgbẹrun ọdun alaafia. Ẹni ti o kọ Iwe Heberu sọ fun ni pe “Isimi kan kù fun awọn enia Ọlọrun,” o si kilọ fun wa pe ki o má ṣe si ọkan aigbagbọ́ ninu ẹnikẹni ninu wa ni lilọ kuro lọdọ Ọlọrun alaaye.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ọdun Jubeli duro fun?
2. Ṣe alaye idi rẹ̀ ti awọn ofin Ọlọrun fi dọgba ni gbogbo ọna.
3. Ki ni ṣe ti Oluwa fi bukun eso oko wọn ni ọdun kẹfa?
4. Njẹ a gba awọn Ọmọ Israẹli láyè lati lo awọn arakunrin wọn gẹgẹ bi ẹrú?
5. Bi a ba ti ta ohun ini kan, nigba wo ni a le rà á pada?
6. Njẹ alejo le ra ohun ini ẹni kan pada?
7. Nipasẹ ta ni a rà wá pada?
8. Nigba wo ni ọdún itẹwọgba Oluwa?
9. Nigba wo ni iwọ rò pe ọdún alarinrin ti Jubeli yoo waye?